# Ìwé Ìròyìn HapMap



Ìwé yí jáde ni orukọ ilé ìsẹ ìwádí Coriell fun ìwádí imọ ìjìnlẹ̀ nínú àìsàn tí o n se ìwádí imọ ijinlẹ lori àìsàn, Apá kẹ̀ta, ọdún 2007


## HapMap sé ayíká ìwádí ìjìnlẹ̀ nípa ìran

*HapMap yí sé ayíká ọ̀nà tí àwọn onímọ̀ -jìnlẹ̀ ndarí ìsẹ́ ìwádí ìjìnlẹ̀ nípa ìran. Wọn tí lo HapMap yí làti rí àwọn ẹyọ-ìran jiini tí o tan mọn ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àìsàn, atí wipé àwọn ìwádí onìléri wa ni ìlọsíwájú. Àwọn àpèjúwe tí a kó jọ fún ìdáwọ́lé HapMap yí ní àwọn ọgọ́rùn awádí nlo láyíká gbogbo àgbáyé nínú àwọn ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìwádí míràn. Àwọn ìwádí yí tùn bọ fun wa ni óyé to jìnlẹ nípa ilana àìsàn àti ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ apá alákọ́bẹ̀rẹ̀ ẹ̀kọ́ oníyè tí àwọn òyìbò mọ sí Biology.*

Láyíká gbogbo àgbáyé, àwọn àwàdí nlo HapMap yí ní àwọn ọ̀nà tìyáratìyára tuntun to lọ́yìn làtí rí àwọn ẹyọ-ìran jiini to sójúùse sí ìlera àti àìsàn. Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ilé ìsẹ ti ìmọ̀-ẹ̀rọ ti ìyè èyí tí àwọn òyìbò mọ sí Biotechnology ní wọn tí sé ìdàgbàsókè àwọn ìmọ̀-ẹ̀rọ tuntun – tí wọn pé ní “platforms” – làtí ìyanjú tí àwọn ẹ̀rí tí HapMap. Àwọn orúpò tí wọn pé ni “platforms” yí fọ̀nàhàn àwọn ìlànà tuntun tó lọ́yìn làtí ya àwọn àpèjúwe DNA yí sọ̀ọ̀tọ̀. HapMap yí tí dá ọ̀nà èbùrù tí o jẹ kí oseése fun àwọn onímọ̀ -jìnlẹ̀ nísìnyí làtí yá àwọn àpèjúwe ẹ̀jẹ̀ làtí ọgọ́rùn tàbí ẹgbẹ̀rún èniyàn pẹ̀lú àìsàn tàbí láìsí àìsàn sọ̀ọ̀tọ̀. Èyí jẹ kí oseése fun wọn láti rídí àjọsepọ̀ láàrín àwọn ìran ọ̀tọ́ọ̀tọ̀ àti àìsàn. Láti àwarí ẹyọ-ìran jiini pàtàkì mèjì to ní àjọsepọ̀ pẹ̀lú oun tí òyìbò mọ sí “macular degeneration” (èyí tí a sé ìròhìn rẹ nínú ìpínfúnni ìgbẹ̀hin ti Ìwé Ìròyìn HapMap), àwọn aséwàdí – pẹ̀lú lílò àwọn orúpò “platforms” tí wọn dà pẹ̀lú àwọn ẹ̀rí tí HapMap – tí se ìpilẹ̀sẹ̀ àwọn ẹyọ-ìran jiini to tan mọ àwọn àìsàn pàtàkì míràn bí:

- Àìsàn nipa t’orí-àìpé tí àwọn òyìbò mọ sí Autism
- Àìsàn ìfun-onjẹ kékeré tí àwọn òyìbò mọ sí Celiac disease
- Àìsàn sísanrajù nìgbà èwe
- Àìsàn Àtọ̀gbẹ
- Àìsàn ìwọ̀-ẹ̀sọ gígan tí àwọn òyìbò mọ sí multiple sclerosis

*Ẹ ma retí apá kèjì*




*“Láti ní HapMap lọ̀fẹ́ àti wíwà lórí intánẹtí fun gbogbo àwọn aséwàdí láyíká gbogbo àgbáyé tun bọ perédàsíwájú ìwádí ìjìnlẹ̀ nípa ìsoògùnonìyè làárin gbogbo orílẹ̀ àgbáyé.”*

- Ọ̀rọ̀ yí wá làtí ẹnu Dókítà Huanming Yang, asiwaju ilé-ẹ̀kọ́ tí Beijing Genomics ti a mọ sí Beijing Genomics Institute.

## Nípa ilé ìwádí Coriell

Ilé ìwàdí Coriell fun ìwàdí ìmọ̀ -jìnlẹ̀ nínú àìsàn ní ìlú Camden, ní ìlẹ Níú Jẹsí (New Jersey), o jẹ ìlẹ ìsẹ ìwàdá àgbàtẹru ti a dá silẹ fun owo ti wọn sí tu ní orúkọ pàtàkì ni gbogbo orílẹ̀ èdè àgbáyé ni ìsẹ ti wọn ti se nípa ìwàdí ẹyọ-ìran jiini àti ìtọ́jú àwọn sẹẹlí. Ìlé ìtọ́jú sẹẹlí wọn ti wọn nlo fun ìwàdí ni o jẹ èyí ti o tóbi ju ni gbogbo orílẹ̀ èdè àgbáyé. O si tun jẹ koko àti èyí ti ko se rọpo fun àwọn àsepàpọ àwọn ogbontárígì onímọ̀-jìnlẹ̀ ni gbogbo àgbáyé.





## Bi ẹ sé le kan si wa

À ran àgbègbè yin lọwọ kan ke si wá pẹ̀lú ifọwọsowọpo àwọn ẹgbẹ àmòyé ni agbègbè yin eyi ti à pé ni Community Advisory Goup, ki a ba lé mọ orísirísi ìròyìn tí o wùn yìn làtí gbọ̀. Dókítà Donald Coppock ni o jẹ asiwaju ìsẹ ìwádí HapMap ni ìlé ìwádí Coriell. Ohùn ni o tun jẹ àlakosó fun àwọn ìwádí àti àwọn àgbègbè ti wọn ba wa sowọ́pọ̀. Ẹ le kan si ni àdrẹsí ti à kọ sihin:

Dr. Donald Coppock<br>Director, Coriell Cell Repositories<br>Coriell Institute for Medical Research<br>403 Haddon Avenue<br>Camden, New Jersey 08103, USA

Àgo rẹ:<br>800-752-3805 ti ẹ ba pe ni orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà<br>856-757-4822 ti ẹ ba pe làti ìlú míràn

Fàksí:<br>856-757-9737

E-mail:<br>dcoppock@coriell.org

Àdrẹsí rẹ ni ìntànẹtí:<br>http://www.coriell.org

# Ẹyọ-ìran jiini pàtàkì ti àìsàn nipa t'orí-àìpé tí àwọn òyìbò mọ sí Autism tí wọn rí pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ HapMap

Àwọn aséwàdí tí se àfẹ́rí ìran ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí o sopọ̀ mọ àìsàn autism nígbàti wọn lò àwọn ẹ̀rí làti HapMap pẹ̀lú àwọn àpẹ̀júwe DNA tí a kójọ làti àwọn ìdílé ti o ní àwọn ọmọdé ti àìsàn yi tí kan. Àìsàn autism yí jẹ àìsàn tí wọn ma nri nígbàkúgbà làárin àwọn ọmọdé. Àìsànn yí ma nfá ìyọnu tó gboró fun rironú, èdèe, oná láti lé fi ara kan àti agbára láti leè ronú pẹ̀lú àwọn ènìyàn míràn. Ótó mẹ̀ta làárin ìkọ̀ọ̀kan nínú ẹgbẹ̀rún ọmọdé làti ọmọ-ọdùn mẹ̀ta títí ọmọ-ọdùn mẹ̀wá ní àìsàn yí yọ lẹnu.

Àìsàn autism yí jẹ ọ̀kàn nínú ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn àìsàn àfijogún t'orí-àìpé. Tí ọ̀kán nínú ọmọ ìbéjì ẹlẹ́yinkan ba ní àìsàn autism yí, bẹ náà ni ìkéjì ná ma ní, fẹ́rẹ̀ mẹ̀sán nínú mẹ̀wá nínú ìrú ìsẹlẹ̀ yí. Tí ọ̀kán nínú ẹ̀gbọ́n tàbí àbúrọ̀ ba ní àìsàn yí, bẹ náà ní ẹ̀gbọ́n tàbí àbúrọ̀ kéjì ní idá lòna màrúnlélọ́gbọ̀n ju àròpín éwu làti ní autism. Sùgbọ́n kóto dísinyí, àwọn aséwàdí ko ní àseyọrí kankan nipá títọ́kasí àwọn ẹyọ-ìran jiini tí o sojúùse àìsàn yí.

Nísinyí pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ HapMap (àti àwọn àpẹ̀júwe làti àwọn ìdílé àwọn ọmọdé to ní àìsàn), àwọn awàdí tí se àseyege ojúùtú pàtàkì. Wọn ri ìyàtọ̀ nínú ìtẹ̀léra ẹyọ-ìran tí wọn mọ sí "MET receptor tyrosine kinase gene" – eyí ní oní àjọsepọ̀ pẹ̀lú `àìsàn autism. Ẹyọ-ìran yí lọwọ́sí ìdàgbàsókè ọpọlọ, lílò ètò òkí-ara àti atúnse ètò ẹ̀dà-onjẹ ara. Ìyàtọ̀ nínú ẹyọ-ìran yí nfá kí ìselópọ̀ ẹyọ-ìran náà dínkù. Àwọn ènìyàn tí o ní ìyàtọ̀ yí lé ní oun tí òyìbò mọ sí "autism spectrum disorders" lọ̀nà ìdá mẹ̀jì ju àwọn ènìyàn míràn. Autism spectrum disorders yí le jẹ eyí tó gboró jù (autism), talágbede tàbí tonírẹ̀lẹ̀ ìdàgbàsókè àìsàn.



*Dókítà Antonio Persico nínú ọ́fìsì rẹ̀*

Gẹ́gẹ́bi ọ̀rọ̀ làtí ẹnu àwàdí àlàsàrò Dr. Antonio Persico tí Department of Experimental Neurosciences ní IRCCS Fondazione, Santa Lucia (ìluu Róòmù, orílẹ̀ èdèe Ítálì), "Àìsàn Autism yí le ní àwọn àjọsepọ̀ onínira pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn oùn ìrandíran àti àgbè-ègbè. Sùgbọ́n eyí jẹ ẹyọ-ìran jiini tí o sé pàtàkì ju nípa bibárátan pẹ̀lú àìsàn autism, làti àsàrò ẹ̀kọ́ nípa ìran ìdílé tí o tobí ju lọ̀ tí wọn tí sé. Ìsẹ́ ìwádí eyí tó gbókànlé HapMap tùnbọ jẹ kí oseése làti rí ojútú àràmàdà àìsàn náà."

# HapMap sé ayíká ìwádí ìjìnlẹ̀ nípa ìran

*làti ewé kíní*

Kó bá gbá wá ní àimọyé ọdún làtí rí àwọn àseyọrí yìí láisí HapMap. Àbárèbábọ̀ àwọn ẹyọ-ìran yí jẹ ìgbésẹ pàtàkì bótilẹ̀jẹ́pé o má gbà ìgbà diẹ kí ìtọ́ka àwọn ẹyọ-ìran jiini yìí kótó le túmọ̀ sí ìwòsàn tàbí ìtọ́jú àwọn àìsàn yìí.

Gẹ́gẹ́bi ọ̀rọ̀ làtí ẹnu dókítà Huanming Yang asiwaju ilé-ẹ̀kọ́ tí Beijing Genomics tí a mọ sí Beijing Genomics Institute, "Láti ní HapMap lọ̀fẹ́ àti wíwà lórí intánẹ́tí fun gbogbo àwọn aséwàdí láyíká gbogbo àgbáyé tun bọ perédàsíwájú ìwádí ìjìnlẹ̀ nípa ìsoògùnoníyè làárin gbogbo orílẹ̀ àgbáyé." Fùn àpẹrẹ, pẹ̀lú HapMap, àwọn àwàdí ní orílẹ̀ èdèe Jèpáànù, àparapọ̀ àwọn ìjọba ti Gẹ̀ẹ́sì (the U.K), orílẹ̀ èdèe Ẹstónía àti ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ orílẹ̀ èdè míràn ní wọn bẹ̀rẹ̀ ilé ìpamọ́ oníyè nlá-nlá làti tunbọ̀ kọ́ ẹ̀kọ́ nipá àwọn oun ìrandíran tàbí àwọn oun míràn tí o nlọwọ́ sí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn àìsàn. Ní orílẹ̀ Amẹ́ríkà, àbásepọ̀ pàtàkì tí àwọn òyìbò mọ sí the Genetic Association Information Network (GAIN) ní wọn dá láìpẹ́. Àbásepọ̀ yí fọkànsí títọ́kasí àwọn ẹyọnú ìrandíran pàtàkì tó wá nínú àwọn àìsàn bí àtọ̀gbẹ, àìpé t'orí, àìsàn tí òyìbò mọ sí bipolar disorder, àìsàn bíbanújẹ́, àìsàn tí òyìbò mọ sí psoriasis, àti àìsàn àkíyèsí (attention deficit) tí òyìbò tun mọ sí hyperactivity disorder (ADHD). Ní orílẹ̀ àparapọ̀ àwọn ìjọba ti Gẹ̀ẹ́sì (the U.K), ìdáwọ́lé tóbárajọ nwo àìsàn nípa ìsọ̀n-àlọ ọkàn, àtọ̀gbẹ type 1 àti 2, làkúrègbé, àìsàn tí òyìbò tun mọ sí Crohn disease àti kólitisí elégbò, àìsàn tí òyìbò mọ sí bipolar disorder, bá ka náà ní àrùn ìfúnsọ̀n, jẹ̀dọ̀jẹ̀dọ̀ (TB) àti ibà ní wọn nwo ní orílẹ̀ èdèe Gánà. Ní Sáínà, orílẹ̀ Amẹ́ríkà àti ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ orílẹ̀ èdè míràn, àwọn awàdí nsọ̀rọ̀ nipá àwọn isé ìdáwọ́lé làti wa àwọn ẹyọ-ìran tó ní àjọsepọ̀ pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ irú arùn akàn.

Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn awàdí káríayé nyẹ awọn àpẹ̀júwe fun ara wọn làti wa àwọn ìdáhùn sí orísirísi fun àwọn ìbéèrè nípa ìyè pẹ̀lú lìlò ẹ̀rí tówa nínú HapMap. Wọn tí pín àwọn àpẹ̀júwe HapMap kárí àwọn ọgọ́rùn àti mẹ̀jìdiniogójì (138) awàdí ní orílẹ̀ èdèe mẹ̀rindinlogún (16) làti Sáínà àti Orílẹ̀ẹ Síngápọ̀ọ títí dé orílẹ̀ èdèe àisland (Iceland), orílẹ̀ èdèe Pólándì, orílẹ̀ South Africa àti orílẹ̀ Spéènì. Àwọn isé awàdí náà bí HapMap fúnraarẹ̀ má fi kún ìmọ̀ wa nípa ìlera ènìyàn àti àti ìbátan ènìyàn.

# Àmì-títayọ to dára ju

## Ìpínfúnni yí tọká sí àwọn àgbè-àgbè mẹ̀rin to nsojúùse nínú ìdáwọ̀lé HapMap.

### Aráa Jèpáànù ni ìlu Tókìò, orílẹ̀ èdèe Jèpáànù

The Japanese samples studied in the first twoNí ìlu Tókìò tí ẹgbẹgbẹ̀rún mèjìlá ènìyàn ngbe ní a tí kó àwọn àpèjúwe t'orílẹ̀ èdèe Jèpáànù jọ. Eyí ní a yẹwó ní ọ̀wọ̀-ọ̀wọ̀ mèjéèjì àkọ́kọ́ ti ìdáwọ̀lé HapMap. Ìlu Tókìò yí ní ìlu tí o tobí ju lọ ní orílẹ̀ èdèe Jèpáànù. Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ọlọ́rẹ àpèjúwe jẹ àwọn ènìyàn tí wọn tí sojúùse nínú àwọn ìdáwọ̀lé ìwádí ìjìnlẹ̀ nípa ìsoògùnoniyè míràn. Sùgbọ́n ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ènìyàn ló sọ̀rọ̀ nipá ìdáwọ̀lé náà pẹ̀lú àwọn ọlọ́rẹ làti àgbèègbè Kanto tó yi ìlu Tókìò ka.

Nígbatí wọn sé ìsọ̀rọ̀ yí, àwọn kankan béèrè nipá bí a o tí sàmì sí àwọn àpèjúwe tí a gbá làti orílẹ̀ èdèe Jèpáànù; wọn kó fẹ kí ìwádí HapMap lọjọ́ iwájú yà àwọn aráa Jèpáànù tó jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ ìpín-kékeré ní àwọn orílẹ̀ èdè tó wa nìta orílẹ̀ èdèe Jèpáànù sọ̀tọ̀. Àwọn ènìyàn míràn tún béèrè nipá ibi-ìkọ̀kọ̀ àti ìgbẹ́kẹ̀lé, sùgbọ́n àwọ̀n ìbéèrè yí dín kù nígbatí o yé wọn wipé a kó ní gba orúkọ tàbi àwíyé nipá ìtọ́kasí wọn rara. Àwọn míràn sọ̀rọ̀ nipá lìlò àwọn àpèjúwe tí a fi pamọ́ wipe nítorí òwò làti àwọn ilé ìsẹ̀ ti ìmọ̀-ẹ̀rọ ti iyè ní àwọn orílẹ̀ èdèe tó wa ní ìwọ̀ oòrùn àti báwo ni ìmójútó to péyé ma sé wa fun àwọn àpèjúwe náà tí wọn ba tí tẹ àwọn ará ilé ìwádí Coriell lọwọ́. Ní ìdáhùn si díẹ̀ nínú àwọn ìbéèrè náà, ilé ìwádí Coriell yí díẹ̀ nínú àwọn ìlànà wọn padà làtí gba àlàyé lẹkùnrẹrẹ làti ọwọ́ àwọn awàdí tó béèrè fun àwọn àpèjúwe náà kí a lé kédè padà fun àwọn ẹgbẹ àmòyé ni agbègbè orílẹ̀ èdèe Jèpáànù (CAG)



*Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ọlọ́rẹ ni orílẹ̀ èdèe Jèpáànù tí sojúùse tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ nínú àwọn ìdáwọ̀lé ìwádí ìjìnlẹ̀ nípa ìsoògùnoniyè míràn.*



*Tẹmpẹlí tí Meenakshi ní Pearland, Texas jẹ̀ ìbì ìpàdé pàtàkì fun àwọn ọmọ- ẹgbẹ́ àgbèègbè aráa Gujaratí Índíà ní ìlu.*

### Àwọn aráa Gujaratí Índíà ní ìlu Houston,Texas

À gba àwọn àpèjúwe tí a ma gbé yẹwó fun ìdáwọ̀lé HapMap ti ọ̀wọ̀-ọ̀wọ̀ tó nbọ làti àwọn ènìyàn tó ngbé ní ìlu Houston, Texas. Àwọn ènìyàn yìí ní àwọn asáájú tó wá làti àgbèègbè Gujarati ní orílẹ̀ èdèe Índíà. Àgbèègbè Gujarati wà ní apá agbede aríwá oun ìwọ̀ oòùn ti ẹ̀ka-ìlẹ̀ t'orílẹ̀ èdèe Índíà. Gujarati jẹ ọkàn nínú àwọn ìpínlẹ̀ tó lágbára ì sọ̀pọ̀ ní Índíà. “Gujarati” yí sì jẹ ọ̀rọ̀ tí wọn ló làti se àpèjúwe àwọ ènìyàn tó tọsẹ̀ ìrandírab wọn si àgbèègbè yí nìbítí àwọn tí nsọ̀ èdè Gujarati.

Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ènìyàn ti a bá sọ̀rọ̀ ní àgbèègbè aráa Gujarati to ìlu Houston béèrè nipá ìwádí-ìjìnlẹ̀ ti ìran ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Wọn sí tun ní ìrètí nipá bí ìwádí yí sé ma fun wá ní ìmọ̀ nipá ìdí àrùn àti bí ìwádí yí sé ma ntun ẹ̀dá ọmọ-aráyé sé. Wọn fẹ̀ sojúùse nínú ìwádí yí nitóripé àwọn ènìyàn tó ní ìrandíran làti orílẹ̀ èdèe Índíà kó fí bẹ ní àyè nínu àwọn ìwádí ìjìnlẹ̀ nípa ìsoògùnoniyè bí àwọn ènìyàn làti orílẹ̀ èdè míràn. Ní pàtàki, àwọn aráa Índíà ti gúúsù Ésíà tó ngbé ní orílẹ̀ Amẹ́ríkà kó fí ní àyè nínu àwọn ìwádí ìjìnlẹ̀ nítórí wipé wọn ma nkó wọn pọ̀ pẹ̀lú àwọn aráa Ésíà míràn. Àwọn ènìyàn tó wa ní àgbèègbè Gujarati tí ìlu Houston ní ìrètí wipé àwọn èsì HapMap yì ó pésé àyè púpọ̀ fun ìwádí nipá àwọn ìyọnu ìlera tí aráa Índíà tí o ngbé nínú Índíà àti ní àwọn orílẹ̀ èdèe míràn kákìrí àgbàyé.

# Àwọn Yórùbá ní ìlu Ìbàdàn, l'orílẹ̀ èdèe Nigeria



*Àwọn ẹgbẹ́ aráa CAG Yórùbá nrètí wipe ìwádí-ìjìnlẹ́ ti ìran ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ má jẹ̀ kí àwọn ènìyàn kákìrí àgbàyé súnmọ́ arawọn.*

Ní ìlu Ìbàdàn tí ẹgbẹgbẹ̀rún mèjì ènìyàn ngbe ní a ti gbá àwọn àpèjúwe tí Yórùbá tí a gbé yẹwó ní ọ̀wọ̀-ọ̀wọ́ mèjéèjì àkọ́kọ́ ti ìdáwọ́lé HapMap. Ìlu Ìbàdàn yí ní ìlu kẹ̀jì tí o tobí ju lọ ní orílẹ̀ èdèe Nigeria. Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn aráa Yórùbá ní ọ̀làjú ènìyàn tí wọn ní ìtàn àkọ́ọ́lẹ̀ àti akọ́dí ìgbìmọ̀ t'osejú àti agbéláwùjọ ẹ̀dá. Àwọn aráa Yórùbá jẹ ogójì ẹgbẹgbẹ̀rún ènìyàn ní Ìwọ̀-oòrùun Áfíríkà, wọn tun jẹ fẹ́rẹ̀ 30% àwọn àráa orílẹ̀ èdèe Nigeria. Nínú ìlu Ìbàdàn, ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ènìyàn ni bẹ̀ jẹ Yórùbá.

Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ènìyàn to wá ní àgbèègbè Yórùbá ti wọn sọ̀rọ̀ nipá ìdáwọ́lé HapMap yí fi tọ̀yàyà sojúùse nínú ìwádí yí. Àlàyè nipá "Out of Africa" ti ìtàn àkọ́ọ́lẹ̀ ẹ̀dá ọmọ-aráyé, àti bi gbógbó ọmọ-aráyé sé jadé làti ìlẹ̀ Áfíríkà je oun pàtàkì to wùn wọn. Wọn sọ wipé ìwádí-ìjìnlẹ́ ti ìran ọ̀tọ́ọ̀tọ̀ ma fí han bí àwọn ènìyàn sé bàràtan àti wipé èsì náà lé jẹ̀ kí àwọn ènìyàn kákìrí àgbàyé fẹ́ràn arawọn. Ní pàtàkí àwọn aráa Yórùbá tabí àwọn ènìyàn míràn tó ní ìrandíran làti ìlẹ̀ Áfíríkà tí ìgbà oko ẹ́rú yá sọ̀tọ̀. O yé àwọn aráa Yórùbá pé o má tó ìgbà díẹ̀ kí àwọn ànfàní ìlera làti ìdáwọ́lé HapMap tó dé orílẹ̀ èdèe Nigeria sùgbọ́n o wun wọn làti sojúùse kí àwọn ìran ọmọ to nbọ̀ lọ̀jọ̀ iwájú lé lànfàní. Àwọn míràn nínú wọn ní ọmọ àti ẹbí sí orílẹ̀ Amẹ́ríkà, orílẹ̀ èdèe Brítéènì àti àwọn orílẹ̀ èdèe míràn. Wọn sí ró wipe àwọn ènìyàn yìí lé lànfàní tí ìdáwọ́lé HapMap yí bá pésé ànfàní ìlera ní àwọn orílẹ̀ èdèe náà.

# Àwọn Tọskaní ni orílẹ̀ èdèe Ítálì

Àwọn àpèjúwe tí a ma gbé yẹwó fun ìdáwọ́lé HapMap ti ọ̀wọ̀-ọ̀wọ́ tó nbọ ní a gba làti àwọn aráa ènìyàn tó nje ìrandíran Tọskaní ní ìlu Tọskaní eyí tó jẹ àgbèègbè nlá ní àárín orílẹ̀ èdèe Ítálì. Àwọn àpèjúwe náà ní a gba làtí àwọn agbélé ìlú onísọ̀pọ̀ lẹ̀gbẹ̀ ìlu Flọ̀rensi, ìlú tó ní ìtàn àkọ́ọ́lẹ̀ làtí ìgbà àwọn Etruscan. Ìlú náà tun ní àmí tolàgbara.

Àwọn ènìyàn tó sojúùse nínú ìdáwọ́lé HapMap yìí jẹ̀ àwọn tí ìdáwọ́lé náà wun bótilẹ̀jẹ́pé wọn kó gbá àlàyé nipá ìsẹ náà. Àwọn èsì tagbéláwùjọ ẹ̀dá ti ìdáwọ́lé yí mù ọ̀rọ̀ wá làti àwọn míràn pẹ̀lú àsàrò nipá oun to jẹ̀ làti jẹ̀ ènì ti o ngbé ìlu, oun to aráa Tọskaní jẹ̀ àti ìwùló oun tí agbéláwùjọ ènìyàn jẹ̀. Àwọn sé ojúùse nínú ìwádí yí fun ìdáwọ́lé HapMap pẹ̀lú ìranlọ̀wọ̀ àwọn àwàdí to ngba àwọn àpèjúwe ná kọ̀ iwé nipá oun tí wọn mọ̀ sí ànfàní àti éwu ìdáwọ́lé yí. Wọn tun sọ̀ àwọn ìfẹ́-ọkàn wọn "... wipé ìwàdi ti wọn yìó sé pẹ̀lú ẹ̀jẹ̀ wa kó ní jẹ̀ fun t'osejú tàbi agbéláwùjọ tàbi fun èrò tológun tàbi fun ètòo bíbí ẹ̀dà-oníyẹ̀."

Ilé ìwádí Coriell ma fi iwé ọ̀rọ̀ yí si gbogbo àpótí àpèjúwe tí wọn fi ránsẹ́ si àwọn àwàdí làti àgbèègbè yí. Fun linkki sí gbogbo iwé ọ̀rọ̀ yí, ẹ wó http://ccr.coriell.org/nhgri/tuscan.html.



*Àwọn ọmọ-ègbè CAG ti Tọskaní sé àsàrò nipá èsì ìdáwọ́lé HapMap fun àgbèègbè wọn.*

# Èsì to péyé fun àwọn àpèjúwe HapMap

Ìsàkóso ilé ìtọ̀ju ní ilé ìwádí Coriell níbí ti wọn tọ̀ju àwọn àpèjúwe HapMap sí npésé èsì nipá bí àwọn àwàdí sé ma nló àwọn àpèjúwe náà lọ̀jọ̀wàju àti bí wọn sé ma tunbọ̀ nrí ìranlọ̀wọ̀ làti àwọn àgbèègbè ọlọ́rẹ (làti àgbègbè ti a pe ni Community Advisory Goup). Ìle ìtọ̀ju yí tí National Human Genome Research Institute (NHGRI) se alábójútó rẹ ni àwọn òsìsẹ́ kan náà làti ilé ìwádí Coriell ní o má sé abójútó làbẹ àsẹ̀ Dókítà Donald Coppock tí oti ni ilé ìwádí Coriell pẹ̀lú ìdáwọ́lé HapMap ọdun tó ju mẹ̀rin lọ. A kó ni yí ibí tí àwọn àpèjúwe wa padà. Sùgbọ́n ìtúntò yí ma jẹ kí osésé fun àwọn òsìsẹ́ ilé ìwádí Coriell làti lé mójútó àwọn lílò àpèjúwe HapMap àti làti lé sàlàyé ní kíkún fun àwọn àgbèègbè ọlọ́rẹ.



*Donald Coppock, Ph.D., àwàdí pàtàkì (òsì) àti Christine Beiswanger, Ph.D., Àwàdí arannilọ́wọ́, (ọ̀tún) pẹ̀lú àwọn òsìsẹ́ ilé ìwádí Coriell Cell Culture Laboratories tó sísẹ pẹ̀lú àwọn àpèjúwe HapMap.*

Àwá yí o sọrọ nípa àwọn agbègbè to ku ti wọn kó pá nínú ìsẹ yí ninu ìwé ìpínfúnni to nbọ̀. Àwá yí o sí tun máà to yìn létí leseẹsẹ nípa ìsẹ àgbàse HapMap yi àti àwọn ìwàdí pàtàkì.

Ẹ o ri àwọn itẹjade iwe iroyin HapMap yi ni ibudo ori itakun àgbáyé ni adresi ti a kọ sihin: http://www.coriell.org/index.php/content/view/65/120/ ní àwọn èdè yìí: Èdèe Sáínà, èdèe Gẹ̀ẹ́sì, èdèe Faransé, èdèe Ítálì, èdèe Jèpáànù, èdèe Spéènì, èdèe Swahílí, àti ní èdèe Yórùbá. Ẹ tun le ri awọn iroyin pataki ni adresi àgbàse gbogbo ori lẹ ede àgbáyé ni orukọ HapMap ti a pe ni International HapMap Project. Eyi jẹ, http://www.hapmap.org.

Coriell Institute for Medical Research
403 Haddon Avenue
Camden, New Jersey 08103 USA
E si le pe ago wa,
Tel: 800–752-3805 ti ẹ ba pe láti orílẹ̀ èdèe Amẹ́ríkà 856–757-4822 ti ẹ ba pe lati orílẹ̀ èdè omíràn
Fàksí: 856-757-9737
Linki wa ni lori intaneti ni http://www.coriell.org